AWON OHUN PATAKI NINU IWEOSE YI
Wọn şi ile Alabiyamọ
Oju iwe 1
Ọwa ki şegbẹ Opẹ
Oju iwe 1
O ye ki amọwe mọ işelu
Oju iwe 2
Openi ni şọla
Oju iwe 3
"Alatike Ijọagbọn
Oju iwe 4
Ojusaju ko dara
Oju iwe 5
Akukọ rọ Ijẹşa lọrun
Oju iwe 6
Eoito kọkọ gbin owu kar
Oju iwe 7
E gbe ẹgbe Akukọ ga!
Oju iwe 8

# IRAWỌ ★ OBOKUN

Vol 4 No 167 ILESHA MONDAY DECEMBER 19 1955 IYE OWO: TORỌ

# OWA SOPE IRO NI WON PA MO ON, O NI ON KO SEGBE OPE

## ỌWA KOŞE ẸGBẸ OPE

Irohin kan wa lati Afin Ọwa pe o ya Kabiyesi lẹnu nigbati wọn sun si leti pe o jade ninu iwe irohin kan lati Eko pe on i di okan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ olopẹ: Irohin na fiyeni pe ohun to şẹlẹ gan ni pe awọn Alhaji Smith, ọgbẹni Ariyọ, J O Lawanson, Lawrence Ọmọle, Samuel Ademilọla, Tumi Haastrup ati awọn miran wa si afin lọjọ lọsẹ to kọja:

Wọn ni nigbati wọn de Afin ti Kabiye jade si wọn niwọn bẹrẹ si iwasu fun pe ki o wọ ẹgbẹ ọpẹ

Irohin na fiyeni pe Ọgbẹni Akọsile, ọkan ninu ẹmẹwa Ọwa ni Afin bere lọwọ wọn pe bawo lose jẹ pe awọn nikan lo wa ma nyọ Ọwa lẹnu lati wọ ẹgbẹ wọn, o sọrọ siwaju pe on ko i ti rano ọjọ ti ẹgbẹ miran rause wa ba Ọwa lati dọmọ ẹgbẹ wọn

Esi ti Kabiyesi fun wọn gẹgẹbi irohin na ti wi nipe Baba ni on ati awọn ijoye on jẹ fun gbogbo ẹgbẹ oşelu ati ẹgbẹ ilu patapata ati Olọpẹ, ati Alakukọ, ati Imọle ati Igbagbọ

Wọn ni Kabiyesi pari ọrọ rẹ wipe ti wọn ba fẹ ki on şe ẹgbẹ kankan ki wọn pe ipade gbogbo ọmọ Ijẹşa, ti Ijẹşa ba ti fọwọ si pe ẹgbẹ yi tabi iyẹn ni ki on şe on yio fe şugbọn ohun to tẹ on lọrun ni lati duro ni ipo baba ti on wa fun gbogbo Ijẹşa Kabiyesi pari ọrọ rẹ pe on kośe ẹgbẹ ọpẹ o .



OBA ALAIYELUWA OWA AJIMOKO KEJI

Ninu iwe wa ọsẹ yi, Kabiyesi Oba Ọwa Ajimọkọ Keji, Adimula Oba Ile Ijẹşa sọ pe iro ni iwe irohin to sọ pe on di Olọpẹ pa mọ on; Kabiyesi sọ wipe Baba ni on jẹ fun gbogbo ọmọ Ijẹşa ninu ẹgbẹ yowu ki olukuluku wa;

USE A SHILLING TO BUY

**THE TRUTH**

A pamphlet, entitled "16 of the Reasons WHY I oppose the Action Group" by Akindele Ojo is ready for sale at G53 Isere St. Ilesha.

## WỌN ŞI ILE ALABIYAMỌ

Wọn ti şi ile alabiyamọ ni Ileşa ni ọjọ karundogun oşu yi ni ile işẹ Post Office atijọ.

Ọlọla ati Olọye C.A Akran ẹniti o jẹ oluşeto itesiwaju işẹ ilu ninu ijọba ti Ekun Iwọ Orun lọ si ile na.

Ninu ọrọ rẹ, o fiye awọn to wa sibẹ pe ijọba Ekun Iwọ Orun ti şetan lati ran ẹnikẹni to ba ran ara rẹ lọwọ.

O ni o dun mọ on ninu pe pẹlu itọwọbapo awọn ọmọ Ijẹşa nile ati idalẹ o şe e şe lati kọ ile na.

O ni inu on yio dun ti awọn obirin ipinlẹ yi ko ba rẹhin nipa imurasilẹ itesiwaju ninu ohun gbogbo, o ni toribẹ ni ijọba şe fi owo pupọ bi ẹgbẹgberun lọna ẹgberun ọọa medogun silẹ fun işẹ idagba soke ilu.

Diẹ ninu awọn pataki to wa nibẹ ni Ọgbẹni ati Arabirin Hansson Ajẹle Ifẹ ati Ileşa, Dr. J. Wright ati iyawo re, Ọlọla C. O. Kọmọlafẹ J. O. Fadahunsi ati aya re, Ọgbẹni J. A Akinyemi. I. O Ajanaku, D. Ọsunloye ati iyawo re.

Rev William, Ọgbẹni M A Akinwumi,E.A Lufadeju Arabirin B. T Ogunseitan, E A Ekunşeitan, ẹniti o ka iwe ikini kabọ; Ati ọpọlọpọ awọn miran:

## AGBERO IBADAN NGBOWO JU

(Lati Ọwọ Kanselọ S.B. Parodoye).

Irohin de etigbọ mi pe awọn Agbero to wa ni ibusọ motọ ni Ibadan ko jẹki işowo motọ rọrun fun awọn onimotọ mọ.

Lẹhin igbati onimotọ ba sanwo ibusọ tan, wọn ni awọn Agbero na ma ngba bi poun meji lọwọ awọn onimotọ pe awọn yio wa ero fun wọn.

Bi o ti jẹpe kosi ero ti ko mọ ibiti o nlọ, igbati ero de e ba ti joko sinu motọ tan agbero yio tun ma bere owo si

Bi onimotọ ba kọ lati fun wọn lowo si wọn koni jẹki wọn lọ Ibiti wọn ba ti ntasiko onimotọ sọrọ ni awọn ero toju ti nkan yio binu sọ kalẹ lati lọ wọ motọ miran.

Awọn onimotọ Ibadan papa ti nsọ pe iwa buburu awọn agbero wọnyi ti su awọn ntoripe wọn ko jẹki işẹ wọn lere.

Nitorina, a fi iyọnu Ọlọrun bẹ awọn alaşẹ ibusọ motọ Ibadan kiwọn bani kilọ fun awọn agbero wọnyi nitoripe awọn kọ lo ni ibusọ motọ.

Emi ko si rope fun anfani tiwọn nikan ni wọn se da ibusọ motọ silẹ: Ẹ gbawa lọwọ wọn o.

## AWỌN ONIŞẸ ITẸWE IJẸŞA ŞE IPADE

Lati ọsẹ kẹta sẹhin ni ikede ti njade pe awọn to lowo sinu işẹ itẹwe Ijẹsa yio se ipade

Wọn şe ipade na lọjọ kẹrindinlogun oşu yi ni gbọngan Obokungbusi lati agogo mẹfa irọlẹ

Irohin lori ọpọlọpọ ohun ti wọn şişẹ le lori nibẹ yio jade nigba miran

## IPADE IJỌBA IJẸŞA LONI

Igbimọ ijọba ti akopọ ile Ijẹşa yio şe ipade loni lati sọrọ lori eto inawo ijọba wọn ti ọdun 1955 si 1957.



OMỌ'BA GBADEBO BẸPO

On ni aşoju Irawọ Obokun ni Abẹokuta. O bẹ Ileşa wo lọsẹ to kọja o si bẹ ibi işẹ itẹwe Ijẹşa wo.

## ŞIŞI "OFFICE" AWỌN KAFINTA

Irohin de ọdọ wa pe awọn Kafinta yio şeto aşeyẹ şişi ile işeto ẹgbẹ wọn lọjọ Jimọ to nbọ yi ni dede agogo mẹrin irọlẹ.

Ipade gbogbogbo ti awọn Kanfinta şe ni Ileşa laipẹ niwọn ti pinu lati fi ikorita işeto ẹgbẹ wọn si Ileşa.

Akọwe wọn agba, Ọgbẹni M. M. Ibokba tide si Ileşa ni ile işeto wọn na ni yio ti ma şişẹ. Gbogbo Kanfinta ni Ileşa ati agbegbe pẹlu awọn olufẹ wọn niwọn pe sibi aşeyẹ işile na.

# FA OGBON YO

## IYA NI IKU TỌṢI TABI IYAWO?

(Lati ọwọ Adebayọ Abe X,73 Oke-Iro Ileṣa)

Mo dupẹ lọwọ Olotu Irawọ Obokun, iwe irohin oloyin mọmọ fun aye ti o gba mi lati ran Ọgbeni Alabi lọwọ.

Nigbakan Iya kan bi ọmọkurin kan ẹniti orukọ rẹ njẹ Alabi, Ṣugbọn ko ju nkan bi ọdun meji ti nwọn bi Alabi ti baba rẹ ti ku Iya Alabi yi ni o nṣe baba ti o si nṣe iya lati tọju rẹ ati ohun ti wọn yio je.

Nigbati Alabi dagba diẹ, Iya rẹ sa ipa rẹ lati tete gbe iyawo fun ni treti pe iyawo na yio bi ọmọ ti o jẹ pe laipẹ jẹjọ nwọn yio di pupọ.

Oko ni Alabi ati iya rẹ ma nro nitori ko si oluranlọwọ fun wọn. Alapi ni ibọn kekere kan ti o ma fi npa bi ẹiyẹ ati ẹranko kekeke. Iya Alabi yi sa gbogbo agbara rẹ o si fẹ iyawo fun Alabi.

Nigbati nwọn ṣe ita ati ije iyawo wọn tan ni iya Alabi ati iyawo Alabi mura lati lọ rin wo oko nwọn. Wọn ko ide bẹ lati igbati wọn ti nṣe igbeyawo.

Alabi gbe ibọn rẹ lọwọ nigbati wọn nlọ. Nigbati wọn de ọna Alabi ri ẹiyẹ kekere kan bi o ti na sọ fun Alabi pe ki o gbọ alaye ti on yio sọ yi ki o le mọ eyiti on yio ṣe. Alabi si mu suru.

Ẹiyẹ na sọ fun pe bi o ba on iya re yio ku ati pe ti ko ba pa on iyawo rẹ yio ku. O ro titi, ṣugbọn ko iti mọ eyiti yio ṣe. Ti o ba gbe ibọn rẹ so-ke lati pa ẹiyẹ na iya rẹ yio ma kigbe pe nigbati o jẹ pe "emi lo bi ọ ti o si tọ ọ dagba, ti mo si sa gbogbo agbara lati fẹ iyawo fun ọ, ti o wa jẹ pe pipa ni iwọ yio fi ṣe ẹsan fun mi."

Ti o ba si fa ibọn rẹ mọra, iyawo rẹ re yio fi igbe ta pe "Ki a le ma gbe pọ pẹlu alafia ati ki a bimọ, ki emi aii iwọ di baba ti iya lẹhin ọla ni iya rẹ ṣe fẹ emi lati ile iya mi wa, afẹpa ni ẹ fẹ mi ni?"

Bayi ri wahala na ṣe ba awọn mẹtẹta ti Alabi ko mọ eyiti on yio ṣe. Ẹ jọwọ, ẹ ran Alabi lọwọ pẹlu alaoe kikun, nitoripe iya ti o bi ọmọ kan ṣoṣo, ti o si fẹran rẹ ju ẹmi, ti o si fẹ iyawo fun ni o yẹ ki o ku ni, tabi iyawo ti wọn fẹ lati le bimọ ki wọn le di puyọ ni.?



ALAGBA J. J. ẸKUNDAYỌ

On ni Baba Isalẹ (Patron) fun ẹgbẹ Kafinta ti gbogbo Nigeria ati Kamarumu Awọn ẹgbẹ na ti bẹrẹ si ṣiṣẹ lori awọn Ipinnu ti wọn ṣe ni ipade ti wọn ṣe koja laipe. Lọjọ Jimọ to nbọ ni won yio si ile iṣeto ẹgbẹ wọn ni E 180 Ẹgbẹdi St Ileṣa ni agogo mẹrin irọle..



KANSẸLỌ GABRIEL ẸṢỌ

On jẹ ọkan ninu awọn loriọmọ Ileṣa o si jẹ ọkan ninu awọn kansẹlọ ti Ileṣa ati apapọ gbogbo ilẹ Ijeṣa o tun jẹ ọkan ninu awọn aṣoju ẹgbẹ iṣelu Alakukọ. Ẹnikan daba ninu Iwe ọsẹ yi pe o yẹ ki awọn ti komọwe to jẹ ẹlọgbọn na lẹnn ninu ọrọ Ilu toripe awọn lo pọ lori ọrọ ilu.

# IRAWO OBOKUN FUN ERINMO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lati ra rawọ Obokun ni Ẹrinm-ati agbegbe rẹ ki o bere lọdọ Ọgbẹni Samuel O. Ogun dele Ọna Ẹffọn No 644 Ẹrinmọ.

## FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbọ gbo Ipade dede.

## OYẸ KI ALAIMỌWE MO NIPA ETO IṢELU

(Lati ọwọ Tim S Oguns Agric Dept Ilesa)

Mo dupẹ lọwọ Olotu Irawọ Obokun ti o gbemi laye ninu Iwe Oloyinmọmọ ti ọsẹ yi Obokun agbe ọ o

Lati nkan bi ọdun melo kan sẹhin ti eto iṣelu ti bẹrẹ ni Ilesa ni awọn baba wa bi Fadugba ati awọn jankanjankan bẹ ti nko le darukọ ti njiya bọ nipa ki ilu le dara ati ki alafia le to awọn ọmọ wọn lọwọ

Nwọn se eto yi titi di ọdun 1940 ti rọbi rọbi fi bẹ silẹ. Awọn ti o si nṣe iṣẹ yi nigbana ni awọn ẹgbẹ atunluṣe ti alaga wọn njẹ Fadugba nitoripe o jẹ ọkan ninu Ọmọwe Ileṣa ati alakikanju enia

O gbọn o si ni oye lori, gbogbo nkan ti nwọn nṣe lasiko na lo dara nitoripe ẹniti o mọ iwe ati alaimọwe lo nsọrọ, gbogbo ohun ti nwọn ba sọrọ le lori lo nṣe.

Ṣugbọn lasiko yi aiye ti di t'Ọpẹ ati Akukọ, awọn alaimọwe (illiterates) ko gbọdọ sọrọ mọ, ti o ba ri ọrọ lati sọ ile ara rẹ ni o ma sọ si

Eleyi mu mi ranti itan kan ti awọn agba ma nlti igbati ọba kan ranṣẹ si Ọba ilu abẹ rẹ wipe didan bi o fẹ bi o kọ ki o gbe oke kan ti o ga to oke Imọ ranṣẹ si on larin ọjọ mẹrin:

Ọrọ na da nkan si arin ilu nitoripe bi Ọba kọ ba gbe oke na ranṣẹ ọga re yi yio ran ogun si.

Nwọn ro titi, ṣugbọn nwọn ko mọ ọna ti nwọn yi o gbe gba ṣugbọn nigbana ọba ni ẹmẹwa kan ti orukọ rẹ njẹ Agiriaṣaṣa, on lo da nimọran pe ki ọba ranṣẹ pada si ọga rẹ wipe nwọn ti mura tan lati ru oke na wa, ṣugbọn ko fi ẹniti o ma gbe oke na le wọn lori ranṣẹ ntioripe awọn ko le dagbe.

Nigbati Ọba alaṣẹ na gbọ o ya lenu o ni talo gbon bi eleyi?

Awọn ara ilu si fi Agiriaṣaṣa ti o je ẹru yi joye kan

Leke gbogbo ọrọ mi njẹ ti ọmọwe aii alaimọ'we ba nṣe ilu pọ mo ro wipe gbogbo eto ni yio dara toripe awọn alaimọwe miran gbon ju awọn alakọwe miran, won si ni oye ati ọgbọn iṣelu lori pupọ nwọn fẹ ṣe ṣugbọn kosi ayo fun wọn

Kabiyesi Ọba Alaiyeluwa Ajimokọ II ati ijoye re, mo tun ki alaga awọn oṣelu Ileṣa, kẹ fun awọn alaimọ'we yi laye diẹ ki awọn na le ma da mọran si ohun ti o ba ma ṣẹlẹ larin ilu nitoripe awọn lo pọju ninu Loriọmọ ilu nwọn si nṣeto ti o ba oju mu ti o si le mu ilu dara wọn

# ROHIN LATI AGBEGBE

ÌPETU-JẸṢA

## IJỌ APOSITELI ṢE IKORE

Irohin koto afojuba
Ni ọjọ kẹrin oṣu Decembe 1955 ti ijọ Aposteli se ikorọ
Ikore na larinrin .Lowurọ ọjọ na nikutuhai owurọ ni ikan agogo mẹjọ abọ ni gbogbo awọn ẹgbẹ Akọrin ti mura jingbindi wọn to si ila gbogbo wọn w. Iru aṣọ kanna wọn bẹrẹ si kọri Akọwọle ni gbogbo wọn gan soke ni ipo awọn akọrin.
Bi wọn ti bẹrẹ si nkọrin ni li aluduru na fọwọ ba lori oke
Ilu bẹrẹ si ndun ni gbogbo awọn ti owa ni isalẹ bẹrẹsi njo Church na fẹrẹ ma gba enia Ijọ na
Apostle Olakanpọ lo se iwasu ọ na ọrọ tofi wasu ni psalm 103 ẹsẹ keji Fi ibukun fun Oluwa iwọ ọkan mi ma ṣe gbagbe gbogbo ore ẹ
Ọrọ na kọ gbogbo awọn towa sibẹ lẹkọ pupọ
Apetu ati awọn ijoye rẹ joko wọn ngbọ ọrọ yi gbogbo awọn to wa nita bẹrẹsi nyọju ni oju fersi
Nigba to se ti alufa na bẹrẹ s nsọrọ irẹ ti Ọlọrun nṣe ni Ijọ Aposteli ni Ipetu ori gbogbo enia wa Alufa to wa nibẹ ni pastor J Olusoj Aluduru na ni Kọla Fapohunda ọga awọn Akọrin na ni Gabriel Abiọdun
Ikore na larinrin ọrẹ ikore ti ọdun yi poju ti ẹṣi lọ
Irohin koto afoju ba

OKE-BODE

## IKORE IJỌ JOHANU LARINRIN

Ni ọjọ kerin oṣu kejila ọdun yi ni wọn ṣe Ikore Aladun ni Oke-Bode ninu ile isin ti Johanu Mimọ Lati dede agogo mẹwa owurọ ọjọ na ni isin na bẹrẹ labẹ akoso Alufa M. A. Oroge.

Ohun ti o fi ṣe akori ọrọ rẹ ni wipe. "Nigbati ikore igbẹhin bade ao ko Alikamọ sinu aba, ao si ko iyangbo sina. Eyiti o tumọ pe Alikamọ ni agbado ti o dara ti ao ko sinu aba iyangbo ni firifun agbado ti ao jo nina.
Awọn ọmọ Ọlọrun Olufọkansin I Agbado ti o dara awọn koṣeku koṣẹyẹ ni iyangbo.
Bi awọn Ẹgbẹ akọrinti nkọrin wọn lọ labẹ itọju Ọgbẹni Arimọrọ Atẹdu ru beni yaworanyaworan (Photographe nfi ẹrọ ti nya aworan oni mana-mana (flashing Camera) nya wọn
Awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ ilu yi ṣe bẹbẹ nipa jijo mọju kedere labẹ itoju Ọgbẹni Gboroode ati Asubiojo wọn jo Konkoma mọju tobẹ ti Ọba ilu fi owo fo ọpọlọpọ awọn to njo lori.
Awọn Olukọ ile iwe yi ṣe bẹbẹ nọ pa igbokegbodo wọn pẹlu iranlọwọ arabirin Ojo Miss F. O. Ojo olukọ ni ile iwe Oke-Oye.

## IJỌBA AKUKỌ RỌ IJẸṢA LỌRUN
(Lati Ọwọ G. Adegbitẹ, Ọjaba Ifẹwara)

Nkan ti mo ri ki nto pe ijọba Akukọ rọ Ijẹṣa lọrun nipe ko si nkan ti wọn ṣe ni ileri fun wa ti wọn ko ṣe fun wa.
Ẹ wo igboro Ileṣa, ka sọ ti dasikia awọn Alakukọ nṣe kisa ni igboro Ileṣa lenu ọjọ mẹta ti wọn un ori aga ijọ yi.

Mo dupẹ lọwọ awọn ijọba NC NC pe igba ti wọn ba wa lara jọ.
Ẹ jọwọ ẹ ba wa bẹ awọn arakoko ti o wa ni Ifẹwara ki wọn ma ṣe jẹki koko ati ẹkurọ wa koja si ilu miran lati giredi.
Bi a ti nwi to yi koko ati ẹkurọ wa nkọja si Ifẹ tabi Ibadan lati giredi.

Gbogbo we lari ka ninu iwe Irohin (Daily Times) pe koko ti Ijẹṣa lo kere ju. Nkan to si nfa na nipe ki a ma ko koko wa o si ilu miran. Ere ori koko wa ni fi ti koja si ilu miran ti ti wọn si lọ n ju tiwa.

Mo foju wo Ifẹ, mo si ri pe wọn ni ako to tiwa. Bi o tilẹ t jẹ pe wọn gbin koko Owe awọn Baba wa nipe bi ọkọ ba ni anfani yio kan aya pẹlu. Nipa bayi mo mọ pe bi Ijẹṣa ba ṣe njanfani ere ori koko to na lo ma kan awọn agbegbe pẹlu.
Ki Ọlọrun ma ṣe jẹki ori olori gba iṣe ti wa ṣe.

Mo bẹ ẹnyin alaṣẹ ilẹ Ijẹṣa ki ba ni boju to eyi lati ṣe wa e ki a le ma giredi koko ni Ifẹwaro Emi ti mo kọwe yi ri ọrọ yi gbaa. ngba ni, ki i ṣe pe, mo gbọ.

## OMI ẸRỌ NFẸ ABOJUTO
(Lati ọwọ T. B Ojo.)

Inu mi yio pupọ bi Olotu Irawọ Obokun ba le gba mi ni aye lati ọs ọrọ diẹ sinu iwe Irawọ Obo—kun ti ọsẹ yi.
O dara pupọ ti awọn igbimọ ijọba Ileṣa ba le gba alabojuto si ẹrọ omi mimu ilu Ileṣa.
Ni ibiti ẹrọ omi yi wa ni gbogbo adugbo Ileṣa ni awọn to nfi enu wọn mu omi ni idi ẹrọ yi ti ba jẹ fun mimu gbogbo enia.
Awọn bi ọlọmọlanke ati oni motọ lo jẹ enia pataki to nṣe eyi.
Ni ilu bi Benin, Eko, Ibadan a Warri ti ẹrọ omi yi wa ni awọn enu ilu wọnyi ṣe ti ṣa ija wọn le ipe wọn ko fi ẹnu mu omi ni idi ẹrọ bẹ na ni pe wọn ke si gba awọn oni motọ laye lati fi omi ẹrọ fọ mọọ wọn.
O da mi loju pe bi wọn o ba ṣe atunṣe eyi ni ilu Ileṣa, ẹrọ omi jẹ ọna pataki ti arun yio fi ma tan kakiri.
Ju gbogbo eyi lọ, omi ti a ṣe fun anfani awọn enia. yio jẹ nkan buburu fun wọn.
Mo fi Obokun bẹ ẹnyin to ntu ilu yi ṣe, ki ẹ ba wa ṣe atunṣe si ẹrọ omi wa.



ỌGBẸNI LAWRENCE AMOKEODO

On ni baba ẹgbẹ awọn Kanfinta ti apapọ Nigeria ati Kamẹrum; Gẹgẹbi ipinu ti wọn ṣe ni ipade wọn to kọja, wọn yio ṣeto ṣiṣi ile iṣeto ẹgbẹ (office) wọn lọjọ Jimọ ti i ṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni agogo mẹrin irọlẹ:

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| | | OJU EWE KINI | | | |
| Igba | 1—12 | 8s. | fun | inṣi | kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6d. | „ | „ | „ |
| Igba | 26—52 | 7s. | „ | „ | „ |
| | | OJU EWE KEJI | | | |
| igba | 1—12 | 5s | fun | inṣi | kan |
| igba | 13—25 | 4s. 6d. | „ | „ | „ |
| Igba | 26—52 | 4s. | „ | „ | „ |
| | | OJU EWE KẸTA | | | |
| gba | 1—12 | 7s. 6d. | fun | inṣi | kan; |
| Igba | 13—25 | 7s. | „ | „ | „ |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | „ | „ | „ |
| | | OJU EWE KẸJỌ | | | |
| Igba | 1—12 | 6s. | fun | inṣi | kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | „ | „ | „ |
| Igba | 26—52 | 5s. | „ | „ | „ |

OJU EWE 4, 5, 6, ATI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.



KANSẸLỌ S B FARODOYE

On jẹ ọkan ninu awọn Kansẹlọ ilẹ Ijẹṣa; On si jẹ ọkan ninu awọn onimotọi motọ wọn nṣowo lọ si Ibadan; O sọ ninu iwe wa lọsẹ yi pe awọnagbero Ibadan ko jẹki iṣẹ motọ pe onimotọ mọ.

## ENIA DUDU NI YIO ṢE WỌLEWỌDE ỌBA

Ninu ikede ti wọn gbe jade ni afin ọba obirin ilẹ Gẹsi a gbọ wipe Ọgagun John Thomas U. Aguiyi-Ironse ti ṣe ọmọ ẹgbẹ kẹrin ti awọn ọmọ ogun Nigeria ni a ti yan gẹgẹbi ijoye ti yio ma ṣe ojiṣẹ fun ọba obirin ilẹ Gẹsi ati ọkọ rẹ nigbati wọn ba ṣe ajo ibẹwo wa si Nigeria ninu ọdun titun.

Ni Umuahia-Ibeku ni Calabar ni wọn ti bi ọgagun yi ni nkan bi ọdun mẹtalelọgbọn sẹhin ibẹ ni o si gbe kẹkọ ki o to tun lọ si ile iwe awọn Aguda ni Kano. O to ọdun mẹtala nisisiyi ti o wọ ẹgbẹ ọmọ ogun, ko si pẹ pupọ ti wọn fi gbe lọ si Freetown ni Saro lọhun

Lẹhin ọdun keje, o ṣe idanwo pataki kan, nigbati o si yege o laṣẹ lati ma ṣiṣẹ ninu ile iṣẹ awọn ọmọ ogun nibikibi. Bi o ti pari idanwo yi wọn ran lọ si ilu ọba fun ẹkọ giga, lati igbana ni o si ti pada si Nigeria, ti o tun ṣiṣẹ kakiri awọn ibudo ọmọ ogun ti o wa ni iwọ orun Africa. Fun oṣu mẹta ni o si fi wa ni ipo ẹniti o mu aṣẹ gun fun Ọlọla John Macpherson ti o ti jẹ Gomina Agba fun Nigeria tẹlẹ. Ọgagun Aguiyi-Irose wa ni ilẹ Gẹsi nisisinyi nibiti o gbe nkọ ẹkọ nipa bi a ti ndari awọn ẹgbẹ ọmọ ogun

## ERE IGBA BỌLU

Ẹ jọwọ ki ẹ gbawa laye lati sọ iba ọrọ diẹ sinu iwe ikede yoruba ọrọ na ni pe ni ọjọ keje oṣu kejila 1955 (7 12 55) awọn ọmọ ẹgbẹ kan ti a npe ni ọmọ ẹgbẹ Irawọ kekeke (young stears club)ba awọn ọmọ Faji gba bọlu (ball)

Inu wa si dun pupọ lati gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Irawọ kekeke (young stars club) fun awọn ọmọ faji ni mẹta pere lai san ọkọkan ninu rẹ

Bi bọlu na ti ṣe wọle niyi.

Ekini lati ọdọ G Ayegbe ekeji lati ọdọ A Ọlọwẹ ẹkẹta lati ọdọ Bady Ade captain

A si dupẹ lọwọ Simple Sunday ti o wa ni ẹh n ati Ade David; ti o nmu bọlu, a si dupẹ lọwọ gbogbo ẹni ti o bawa gba ball na lai da ẹnikan si

A si dupẹ lọwọ oluko wa P Ọdẹyẹmi to fun fere fun wa ni ọjọ na

A dupẹ lọwọ Olotu Irawọ Obokun fun iyanju to gba wa.

## WANTED

ECRETA RY /Tarsurer Minimnm qualificatoin Middle II with a good knowledgee of English. Apply befor 26/12/5 to the Chief Aṣireyun Chairman Muroko Local Council Via Anglican School "A" Iṣọna, Ilesha.

CHAIRMAN

## OLOYE LỌKIRAN KU

Ni aipẹ yi ni irohin tan kalẹ pe Oloye Lọkiran ti Orikiran ku ni ile rẹ

Lati ọjọ to ti ku na ni awọn ọmọ ebi ati awọn ana rẹ ti nde lati idalẹ.

Kansẹlọ Michael Falọpe Lọyin Orikiran ni Baba nsinku nibi isinku ra. Lati igbana ni on na ti wa nile

## ẸGBE ẸGBẸ ALAKUKỌ GA

(Lati ọwọ Samson Ọlatunji Adeniji. NCNC Field Sec)

Mo ki olotu ati gbogbo ọmọ Yoruba pe ẹku ipalẹmọ ọdun.

Ẹgbe Akukọ ga nitori ki iya ma jẹ wa o. Orukọ ni nroni nigbati Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC, Party of Common Man) fẹ mu ami wọn nwọn mu Ami Akukọ. Ẹgbẹ yi jẹ Ẹgbẹ ti o nkọ si awa enia dudu pe akoko to lati ji loju orun

Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) lo ṣọ pe o ṣe e ṣe fun enia dudu tabi adulawọ lati ṣeto Ijọba fun ra rẹ. Awa la kọ ṣọpe o ṣe e ṣe fun enia dudu lati wa nipo oyinbo

Awa na lotun kọ ṣọpe o ṣe e ṣe fun enia dudu lati da iṣẹ Iṣowo nlanla bi ti Ila-orun (East) Awa la kọ ṣọ wipe o tun ṣe e ṣe ki ayc enia dudu oniṣẹ Ọlọrun ga de ipo BISHOP

Nigbati Ẹgbẹ Alakukọ ti nkọ (NCNC) Baba wa agba o di ologbe alagba Ọlọla Adeyemọ Alakija ti o jẹ baba ẹgbẹ ọmọ Odudua ati baba wa Ọba wa ni Ife Kabiyesi Ọlọla Adeṣoji Aderemi ṣọ ninu oṣu January 1948 pe o di ọdun mẹdọgbọ ki awọn to tọ fun ominira. Bẹni awa ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) lo kọ kọ ṣọ ninu oṣu kanna (January 1948) ninu ipade nla ti aṣ ni Kaduna (Northern Region) a o ni ominira ni ọdun 1956.

Ami pataki ni Akukọ jẹ nipa ifidimulẹ igbagbọ. Nitorina, mo ni igbagbọ wipe ti a ba gbe eto Ijọba ipinlẹ yi le ẹgbẹ Alakuko lọwọ ao ni ominira. A o tọ ni ẹniti yio le ma ṣe ohun elo fun ara wa

Koko nikan ni igi ọla ati owo wa nibi ṣugbọn awọn onikuṣa (Gold miners) ti fẹrẹ hu ti oko ẹlomi tan Bẹni awọn ti Ijọba wa lọwọ nwọn, mọ wipe, ibẹ ni owo ti nwa fun ẹnyin Agbẹ, ibẹ ni ọla nyin wa

Mo ni igbagbọ pe bi ẹgbẹ wa (NCNC) ba gba Ijọba lagbara Ọlọrun ati lagbara ajumọṣe awa Yoruba, nwọn yio ṣe eto iranlọwọ fun ẹnyin Agbẹ ati fun awọn to ka iwe ti nwọn ko le fi iwe na ṣiṣẹ

Ẹ jẹ ka jumọ fi eto Ijọba fun ẹgbẹ Alakukọ ki nwọn le ṣe anfani fun ẹnyin Agbe iwọ, Mẹkunnu bi emi na papa Ki a le ni anfani lati le diye le nkan wa, lati le ṣe okan funra wa

ẸDIBO FAKUKỌ O

## ỌṢỌBU JẸBI IGBESE

Lọsẹ keji sẹhin ni wọn pari ẹjọ ẹsun igbese ti wọn fi kan Ọgbẹni Ọṣọbu ti o ntun kẹkẹ ṣe lorita ọna Iṣida l'ọja Ọba.

Ẹsun igbese na nipe Ọṣọbu ko san owo ihaya ṣọbu to ti nṣiṣẹ lati ọdun mẹji sẹhin; Aropọ owo na si jẹ ogoji poun.

Lẹhin igbati adajọ da Ọṣọbu lẹbi igbese na tan, o tun fi poun marun ati ṣile marun ha fun pe ki o san fun onigbese rẹ tori wahala to fi ṣe.

Lẹhin na adajọ bẹ onigbese Ọṣọbu pe ko jẹ ki o wa ṣọbu miran titi di oṣu kini ọdun to nbọ nigbati o le le jade, o rile ko rile.

A gbọ ni ibi pataki pe Ọṣọbu ti nbẹ kotu pe ki wọn jẹki on ma san owo na diẹdiẹ

## AWỌN ỌJỌ ỌJA

——:o:——

DECEMRBE 19

Ijẹbu-Jẹṣa Ibodi, Ibode, Kajọla.

DECEMBER 20

Ẹsa-oke, Ilaṣẹ, Ẹpe, Ilọba Iperindo, Imuroko, Ẹrinmọ. Iloko,

DECEMBER 21

Idominasi, Ijẹbu-Jẹṣa, Oṣu, Itagun, Odogbo, Idọka; Iloko Igangan

DECEMBER 22

Ẹsa-oke, Iwara, Ẹjiọrọ, Odo, Ibokun, Ẹsa-odo;

DECEMBER 15

Ijẹbu-Jẹṣa, Inodi, Ibode, Kajọla, Etiọni,

DECEMBER 21

Ẹsa-oke, Ilaṣẹ, Ẹpe, Ilọba Iperindo, Imuroko, Ẹrinmọ, Iloko

DECEMBER 24

Idominasi, Ijẹbu-Jẹṣa, Oṣu, Itagun, Odogbo, Idọka, Iloko Igangan

DECEMBER 25

Ẹsa-oke, Iwara, Ẹjiọrọ, Odo, Ibokun, Ẹsa-odo,


## FOR SALE

——0——

The Temidire Bookshop Almanac for 1956 is ready for Sale at 6d a copy, 5/- a dozen & 50/- a gross obtainable at B 74, Okesha, Street P. O. Box 101, Ilesha.


Printed and Publish^ed by Ijesha Press Ltd., B149 Okesha Street, Ilesha 19 -- 12 - 55